# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. IV. No. 173 SATURDAY, NOVEMBER 7, 1925. 4d

***The People's Leading Vernacular Paper.***

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ileke Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹke Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Pidan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjokun, Ileke Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Iş'ọşọ, Ero Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹla (*Candles*) ati ẹgbagbeje oja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa'wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni :— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy)

## *Electric Novelties.*

Mr. M. SADIKU has assorted kinds of Electric Materials, 2 & 3 lights, Brackets, Shades, etc., too numerous to mention.

He undertakes the contract of wiring houses at very reasonable prices.

And has also in stock louder bells complete with wire and Salamonical ready for connections. Call at 18 Ọbun Eko Street, Lagos, for your selection.

*P.O. Box 378.*

## WHO SAYS TOOLS?

Ọgbẹni J. O. BANKỌLE ti Daddy Alaja *Street, Lagos*, ni wabiwọsi nin işẹ *Carpenter*, fun tita, awọn irinşẹ bi Kọkọrọ, *Rachet Braces, Coffin Handles, Wall Papers*, ati bẹbẹ lọ. Ọpọku ọyọku ni owo wọn.

Jòjò nyaju ni wọn.

# OPEN AGAIN

**AND IN**

# FULL SWING

# LEVER

# STORE

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oșu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oșu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranșẹ si *Editor*.

ONINI BABA EWU.

Ọgbẹni D. L. Oshodi ti 36, Idoluwo *Street, Lagos* ni orișiriși *Ivory Coat & Trouser Button* (Onini) fun tita kosi asọ ti ko ni *button* to yẹ. O si ni wabi-wọsi ero-ija *Tailor* (*Tailors Trimmings*) ni tita bakanna; o si nfa'sọ șe *button* (*Press Coat Buttons*) ki awọn af'asọ-dara (*Expert Tailors*) mașe jafara lati ba ra tiwọn; ọpọku-ọyọku ni ọja meremere wọnyi.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

IBUKUN NI FUN AWỌN OKU!

Ijọba kede Iranti-ọdọdun ti a ma nsaba nșe fun gbogbo oku t'Oyinbo t'Enia Dudu ni akoko ogun Ajakaiye 1914 titi fi de 1918: Alaruba (*Wednesday*) ọsẹ to mbọ ni ọjọ ti ọdunni bọsi; a si sọpe gbogbo awọn ọșișẹ Ọba ati awọn Onișowo yio nàyẹsá nitoripe ki yio si ișẹ lọjọ na. Isin-Akanșe fun abọ wakati eyini ni lati agogo mẹwa abọ titi lọ de mọkanla arọ yio wa ni Ile-Isin Ijọ Onidunkun Oyinbo (*St. Paul's Breadfruit*). Alașẹ Ijọba ati gbogbo awọn Alada nla ni yio lọ sibẹ tawọn ti asọ oye wọn; nigbati o ba di agogo mọkanla gãn, a o rọgbà meji leralera, lẹhin eyi idakẹrọrọ yio wa fun ișẹju meji, ninu eyiti a o șadura fun awọn ara wa na t'Oyinbo t'Enia Dudu, lẹhinna, awọn Asọja yio fọn fere arò, agba kan yio si tun ró lori ẹkẹta; bi a o ti șe nilẹ yi lọjọ na ni nwọn yio si șe nilu Oyinbo, Ọba King yio fi odòdó-òlòrun-didun le oju ẹgun ti a kọ fun iranti awọn to ti șubu loju ija na. Sẹkitẹri Agba nilu Ọba Oga awọn Gomina yio si șe bakanna fun gbogbo ilu ati orilẹ-ede ati èdè ti nwọn mbẹ labẹ asia Ijọba Gẹsi ni gbogbo agbaiye.

Ọlọrun Ọba ye,—
Ọlọrun Ọba jọ o—
Jẹ k'a roju șikẹ ẹhin oku
To ku s'ogun o!
Oke réré, ọmọ-ọba
A nlọ juba ilẹ!!!

AKỌNTA ỌLỌKỌ NPOWE!

Rogbodiyan mimu ti a sọpe awọn Ọlẹlẹmuyẹ mu Akọwe kan ti o nșișẹ niti awọn Oyinbo Jamani Ọlọkọ ti Ita Apọngbọn kan ni; ẹsun ti a sọpe nwọn fi sun ni pe o da Akọntà eyini ni Iwe-ișiro-owo rú. *Monday* ọsẹ yi si ni a gbọ pe awọn Akẹran șe ișẹ na. Baba șọ ni!

IBOSI ỌRỌPA, ỌRỌPA O!!!

Igbe ti awọn enia kan fita ni alẹ Satide to kọja leyi nigbati awọn Igara lọ fọ șabu Ọgbẹni Ogunlana ti Onikoro *Street* ti nwọn ko *beer* diẹ ati sarotu lọ șugbọn ọwọ wọn ko tẹ owo kọkan nibẹ. Ọgbẹni Ogunlana, o ku ewu.

ABỌ O, AJIRERA.

A ba Ọgbẹni A. B. Laotan ti ibi ișẹ Messrs. Niger Coy., yọ fun ọmọbirin titun ti Mrs. rẹ fi ta lọrẹ ninu ọsẹ yi. Ki Ọlọrun wo ju wa lọ o.

KERE O!

Iya-afin Mrs. Beckley ngu Akara didun (*Cake*) ta nile rẹ, ni 53, Opopo nla, õ gbeyawo ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ. o sami fun ọmọ ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ: o tọrọ ọmọ ni o, re yan tirẹ nibẹ.
Ọpọku-ọyọku ni owo rẹ.

## ALUFA JONNY ṢE OHUN ARA.

Ni ọjọ *Thursday* ti o kọja Ẹni-ọwọ Rev. J. R. Williams ati Teacher rẹ kan ati awọn Ẹgbẹ Obinrin ti *Church Baptist* lọ mu diẹ ninu iṣẹ ẹmi ṣe, nwọn si pada ni ọjọ *Teusday* ọsẹ yi, ni ọjọ *Wednesday* ti a ni ipade adura ti Alufa bẹrẹ si rohin Adó ti nwọn ti lọ gbogbo eti ti o gbọ ọrọ yi daradara ni inu wọn dun fun irohin yi. Anu ọpọlọpọ lo ṣe ni fun irohin ọdọmọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Ọpalẹyẹ ọdọmọkọnrin yi ti jẹ Onigbagbọ ri ni iwọn ọdun 1909, gẹgẹ bi Alufa ti sọ nigbati Ologbe Rev. L. M. Stone fi wa l'aiye o si ti jiya pupọ ki Igbagbọ ba le wọ Ilu Adó nigbana ko si Onigbagbọ rara nibẹ nwọn si korira Onigbagbọ ọdọmọkọnrin yi si gbiyanju pupọ pe ki Igbagbọ le wọ ibẹ awọn Abọriṣa si mu wa si Eko ni ẹsun wipe o nba ilu jẹ, a si ti mọ'le fun ọgbọn ọjọ ki wọn to dasilẹ.

Ṣugbọn nigbati inunibini pọ si jọjọ o di Imale ki nwọn ba le fi ni ọkan balẹ o dapọ mọ awọn Imale ibẹ. Ṣugbọn nigbati awọn enia wa de ọhun, o rohin gẹgẹ bi on ti ṣe wahala pupọ lati di Onigbagbọ ki on to wa di Imale. Ọdọmọkọnrin yi si mu wọn lọ si ọdọ iya ọlọya kan ti o fun wọn ni ilẹ lati fi kọ Church si, bi iya yi si ti ri wọn bẹni o bẹrẹ si ki wọn ti o si nyọ wọn gẹgẹ bi ẹni wipe o ti mọ wọn ri nibikan; ohun ti o yani lẹnu nibẹ ni wipe iya ọlọya sọ wipe on ko ti mọ ibiti on ma kẹhin si, eyi fihanni dajudaju pe Igbala wa fun Abọriṣa.

Bibeli papa si sọ wipe awọn Abọriṣa yio sare wọ Ijọba Ọlọrun, Ọlọrun jẹ ki o le ri bẹ o. *Amin.*

Ẹ jọwọ, ẹ ba mi fi ohun Orin Ibilẹ kọ orin yi.

Ọlọya iba jẹ mọ Ọlọrun
Bawo ni iba ti dun to bawo.
Oniṣango iba jẹ mọ Ọlọrun
Bawo ni iba ti dun to bawo.
Ọlọbatala iba jẹ mọ Ọlọrun
Bawo ni iba ti dun to bawo.

Ẹ jọwọ ẹ ba ni gba adura fun wọn ki Ọlọrun le ṣe ọna wọn ni rere fun eyi ti wọn tun nlọ fun ni ọsẹ to mbọ ni Ijẹbu ni nwọn nlọ, ki Ọlọrun ninu ànu Rẹ ki o le jẹ ki awọn ẹmi eṣu le ma tẹriba fun wọn, ki nwọn le ma yọ ti wọn ba mbọ lati wi fun wa pe awọn ẹmi eṣu tẹriba fun wọn; ki awa le ma wi gẹgẹ bi Jesu ti wi fun awọn ọmọ ẹhin rẹ nijọkinni pe ẹ kuku ma yọ nitori a kọ orukọ nyin sinu Iwe-iye l'Ọrun.

Ipari ọrọ wa, ẹ ba mi fi orin yi si ipari ọrọ wa.

F'igbala rẹ fun wa
F'igbala rẹ fun wa
'Nlo yẹ wa o,
F'igbala rẹ fun wa
'Nlo yẹ wa o,
F'igbala rẹ fun wa.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ISAAC IDOWU GEORGE.

### TELEGRAM

SECRETARY OF STATE, LONDON, TO GOVERNOR, LAGOS
DATED 20TH OCTOBER, 1924.

20th October. His Majesty has approved following arrangements for observance in this country Armistice Day November 11th. (i) Short Service will be held at the Cenotaph on the lines adopted in the previous years including Hymn "O God our help in ages past." His Majesty the King will be present and will lay a wreath (ii) two minutes' silence will be observed at 11 a.m. Local authorities in this country will be asked to arrange for suspension of all vehicular traffic for two minutes from 11 a.m., but rail and water transport will not be suspended.

I propose to lay wreath on behalf of the Colonies and Protectorates.

SECRETARY OF STATE FOR THE COLONIES.

### TELEGRAM

SECRETARY OF STATE, LONDON, TO GOVERNOR, LAGOS
DATED 19TH OCTOBER, 1925.

His Majesty has approved arrangement for observance in this country of Armistice Day 11th November on same lines as last year see my telegram dated 20th October, 1924.

SECRETARY OF STATE.

## THE NEW DAILY NEWSPAPER FOR LAGOS

It has been common knowledge for some time in Lagos that an influential limited liability company has been formed for the purpose of producing a responsible daily newspaper in Lagos which is intended, when produced, to include *Reuter's Telegrams*. The arrangements for its production are being pressed forward, but it will not appear until June 1st next. Its title will be the "Nigeria Daily Times," and it will have the support of all the leading African and European interests, not only of Lagos but throughout Nigeria.

Since the preliminary arrangement for this daily newspaper with its special cable service, have been made, it has recently been announced that another daily newspaper is to appear, and intending subscribers and advertisers are cautioned against confusing this with the "Nigeria Daily Times."

ALAKIJA AND ALAKIJA.
*Solicitors for the Proprietors of the "Nigeria Daily Times"*

## IWE-IROHIN OJOJUMỌ FUN EKO

O jẹ ọran to ṣe oju Ilu ti ko farasin lati sọ pe awọn A-tofiletọ ninu awọn Gbajumọ ati Olowo ilẹ yi ti da Ẹgbẹ kan silẹ ti yio ma ṣe Iwe-irohin Ojojumọ l'Eko ninu eyi ti ao ma ri Waya Ojọjumọ (*Reuter's Telegrams*) bi nkan ti nlọ si ni gbogbo agbaiye ka ati oniruru irohin miran. A si wa lẹnu yiyọri iṣẹ yi nisisiyi, Iwe-irohin na ki yio si le jade titi oṣu Ojo (*June*) ọdun to mbọ. Orukọ ti yio ma jẹ ni *Nigeria Daily Times* eyini ni *Irohin Ojojumo ti Ile Odo-Oya*. gbogbo t'Oyinbo t'Enia Dudu onipo ni yio si gbaruku ti

Iwe-irohin na, ki iṣe l'Eko nikan, bikoṣe jakejado gbogbo Nigeria.

Lati igbati a ti wa lẹnu iyọri iṣẹ yi ni awọn kan tun kede pe awọn ndaniyan lati ma se Iwe-irohin Ojojumọ; ki awọn enia wa ti nwọn nfẹ ma gba tiwa tabi ti nwọn yio fẹ polowo ọja sinu rẹ nigbati o ba ya ki o ma ba ma ṣe kilakilo pe tiwa leyi tabi tiwa kọ, ni a ṣe ṣe kilọkilọ yi pe irufẹ Iwe-irohin ti awọn kan kede rẹ na ki iṣe ti sakani wa rara.

ALAKIJA ATI ALAKIJA,
Lọya fun awọn Olotu
"Nigeria Daily Times."

---

## ẸSỌ-DI ỌWỌ NYIN ẸNYIN AWA *MOTOR* L 942 ATI L 441.

Lati ọwọ TẸNI-MASUN-WỌN-KIGBỌ.

Ohun ti ari nipa awọn Mọto L 942 ati L 144 ni wipe ni ọjọ ọsẹ ti o kọja, ni ari oriṣiriṣi iwa abuku ti nwọn fi kan awọn Ero ti on wọ Mọto lati *Ebute Mela* de Eko. Adehun ni adehun njẹ niwọn igbati ẹ ba ti gba owo tan lọwọ ero ti o ba wọ Mọto nyin kosi ara ti ẹ ko le da. Ẹ le wipe Mọto nyin bajẹ tabi ki wọn bọ silẹ ẹnikan ran ṣẹ wa wipe on fẹ gba; nitorina ni a ṣe wipe adehun ni adehun njẹ, bi ẹ ko dẹhin lẹhin iwa aibikita fun enia bayi—ọpọlọpọ igba ni awọn Ọga nyin, yio ma bayin wi fun aita tabi airi enia gba to, bẹni Ọga nyin ko bayin tẹ koto ọrọ ti o le fi mọ iwa adọnkiya nyin si awọn ero ti onjẹ lọ si Eko tabi wa si *Ebute Mela*.

## YEPA! ABIAMỌ KU IRỌJU ỌJỌ IKUNLẸ.

Ni ọsẹ ti o kọja lẹba ọna ọgba awọn were ni Yaba, ni a gburo ariwo idagiri kan lati ọdọ awọn obinrin ti wọn lọ nọ ọja Imoṣin, wipe ọkọ Reluwe lokun enia yan-na yan-na, a ṣe ibere wipe tani ẹni na, ni awa gbọ pe ọkọnrin kan ti ọwọ ati ẹsẹ rẹ rẹjẹ, ti awọn ọmọ wẹwẹ npe ni Ọmẹkẹ ni ọkọ Reluwe na pa l'apa dọrun alakeji. Ki Ọlọrun fi ọran mọ bayi o. Amin.

## IRE ỌMỌ BIBI YIO KARI WA LỌKỌNRIN ATI LOBINRIN. AMIN.

Tayọtayọ la fi ki arakunrin wa Mr. Eṣubi, Akọwe awọn Oyinbo Alagbọn ti Ita Balogun ati iyawo rẹ Miss Ibitọla George ọmọ Ọgbẹni Williamson George, aburo Aranṣọ (*Tailor*) A. W. George Aji-ṣe-finni ti Massey Street, yọ pupọ fun dida si ti Ọlọrun da wọn si pẹlu ọmọ titun lati lọ ṣe idupẹ ni *Church* Iṣọla (*The Brotherhood*) ni alẹ ọjọ Isinmi ti o kọja lọhun. Ki Ọlọrun da awọn obi ọmọ na si fun wa o. Ni agbara Baba a o jade ẹyẹ bayi fun ọmọ awa papa. Amin.

## Ẹ KU AṢEYẸ ỌJỌ O.

A ki Mrs. Frank John ati iyawo Ọgbẹni Glover fun aṣeyẹ ọjọ nipa sisin Ọba wa Ibikunle Akitoye II lọ si *Church* Onidunkun (*Breadfruit*) ni ọjọ osẹ ti o kọja nipa ṣiṣi Angẹli Ikawe (*Angel Lectern*) kan fun iranti baba ati iya *Lawyer* wa Akiṣemọyin—Ẹnikeji ko si botiri ni, ni ọjọ na, awọn obinrin wọnyi yẹ Ọba wa Ibikunle Akitoye II pupọ. Adura wa ni ki Ọlọrun da ẹmi awọn obinrin wọnyi si fun wa, ki Ọba wa si pẹ lori oye. Amin, Aṣẹ.

## Ẹ KABỌ O.

Mr. Luigi Ambrosini ọkọnrin rọgbọdọ Olowò Messrs. L. Ambrosini Ltd., Eko, o ba ọko "*Abinsi*" de ni ọjọ Alamisi ọjọ kọkandilọgbọn oṣu *October*, o si fi Eko silẹ lọ si ilu awọn Gambari (Kano) ni ibi ti o fi ṣe ile baba owò rẹ. A ki awọn akọwe rẹ ni funfun ati ni dudu ẹ ku afojuba Ọga nyin o. Odumare a ba nyin to ti nyin labẹ o.

## Ẹ KU ILE DE O.

A ki Ọgbẹni wa Thomas Phelan (Jnr.) Akọwe awọn Oyinbo Ọlọṣẹ, Apapa, o ku ilede iyawo rẹ Miss Janet Phillips ọmọ Ọgbẹni wa Mr. Phillips ti Ita Balogun a-du-ma-dan, ti o da kan lọ si Ibadan ni ọsẹ yi fun atẹgun oṣu meji tabi mẹta pẹlu ọmọ ọwọ rẹ. A fi adura wa sin yin o. Ki Ọlọrun ṣọ wa ka tun pade. *Amin.*

## KI OLUWA RERE GBA WA LỌWỌ AGBAKO AIYE.

Ni aṣalẹ ọjọ ọsẹ ti o kọja ni a gburo wipe *Motor* awọn Oyinbo kan kọlu Ogunlade Akọwe P.W.D. Iddo, *Motor* na si pa lara, awọn Oyinbo oninu rere na si gbe lọ pẹlu *Motor* wọn na lọ si *Hospital* ni ọdan. Adura wa ni wipe ki Ọlọrun fun ni alafia ara lile o, ki o le pada bọ si ẹnu iṣẹ rẹ. *Amin.*

## ETI ỌBA NILE ETI ỌBA LOKO.

Ọrọ oke iwe wa yi lo tọkasi ohun ti a fẹ lati wi yi—Ni ipari oṣu *October* ni eti wa gbọ wipe Ọgbẹni wa Ọpẹlẹngẹ J. Daniel Akọwe Oyinbo W. B. MacIver Iddo fi iṣẹ silẹ lati bẹrẹ owo (*trade*) ni ṣiṣe. Adura wa ni wipe ki Ọlọrun gbọwọ rẹ si oke o. *Amin.*

## ỌMỌ OLOKU ABAJA LỌRUN.

A ba Iyawo Ọgbẹni wa J. A. Oshodi ti Agoro Street, kẹdun iku iya rẹ ti o ṣẹlẹ ni ọjọ kẹrin oṣu yi, ki Ọlọrun gbe iya na si afẹfẹ rere o.

Mr. J. A. Oshodi oku iya yi tirẹ ni o, ki o ba wa sin oku na lasin gbadun, ki akara Oyinbo ati omi aladidun na kọlura wọn.

## ILE NI ABỌ ISINMI OKO.

A ki *Doctor* Oluwọle ati *Lawyer* Johnson ku afojuba ọrẹ wọn *Lawyer* Franklin ti o ti dakan.

lọ si ọna ilu oke fun iṣẹ rẹ, o si ti pada bọwa ile ni ọjọ kẹrin oṣu *November* pẹlu ara lile, ẹnikeji, niba firi ti a ri on pẹlu *Lawyer* Johnson ninu Mọto a ri wipe o ṣe pẹki diẹ loju wa, a si ni ero wipe atẹgun ọna ilu oke ba lara mu pupọ. Ki Ọlọrun fi *Lawyer* Franklin jinki wa o. *Amin.*

AFRICAN UNITED METHODIST CHURCH
Ẹ KU ILE DE O.

Alufa wa I. O. Oyekunle ti Ijọ Ọmọ Ibilẹ Eko, o da kan lọ si Ibadan fun Isin Ikore Ṣọṣi wọn ni Ibadan a fi oju sin Alufa wa yi o.

Jọwọ Alufa ma gbagbe lati fi oju ikore tiwa ranṣẹ sile o.

TẸNI-MASUN-WỌN-KIGBỌ.

---

Agbado Station,
4th November, 1925.

To
The Editor,
*Eko Akete,*
Williams Street,
Lagos.

Dear Sir,

Kindly publish the attached in your valuable journal at your earliest convenience and oblige.

Yours sincerely,
A. B. COLE.

To
The Editor,
*Irohin Eko Osose,*
Lagos.

Dear Sir,

In your issue of the 24th ultimo, a correspondent by name "Ọmọluwabi" made the following statement *inter alias*

"Nigbati Cole ti o fun jẹ ọkan ninu ọmọ ogun Otitọju—ti o lọ jeri—ti Cole ko ya wa lẹnu, nitoripe bi enia ba ri Igo *beer* kan fun Cole iṣẹ ya."

Will your correspondent "Ọmọluwabi" state clearly to which Cole he alludes as the writer is also a Cole, resident at Otta Road, Agbado Station.

Thanking you Mr. Editor for space allowed.

Yours sincerely,
A. B. COLE,
Agbado Station.

---

Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street, begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!

Cable Address:—
"ỌTAORỌJU" LAGOS.
KARIMU KỌTUN,
P.O. Box No. 505,
3, Docemo Street,
Lagos, (Nigeria.)
"Indents House."
Import of General Lines, and Export of Produce Commission Agencies undertaken, Correspondence Invited.

The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA
Manufacturers of
NEPTUNE
PALE SOAP
BUGLE
PALE SOAP
MAGNET
CARBOLIC SOAP
will send Price Lists and terms to merchants upon application to
P.O. Box 522
Lagos
Nigeria
P 393

GUARANTEED

THE RALEIGH

FOR EVER



# RALEIGH

## THE ALL-STEEL BICYCLE

MILLER BROS. (L'pool) LTD.,

LAGOS.

# EKO AKETE

Eko, Saturday, November 7, 1925.


## OGUN BURU ILŨ KO DUN, PAGIDARI!!!

Laifi ọrọ bọ'po bọ'yọ, gudugbẹ to ja nilẹ yi larọ Satide ijẹjọ nipa fifi sẹwọn ti Adajọ Agba fi Ọgbẹni Thomas H. Jackson si fun oṣu meji pẹlu sisan pọnun mẹdọgbọn (£25) sapo Ijọba ko ṣai mu ẹnikẹni to ba gbọ takiji; ẹṣẹ ti a si fi sun ni pe ninu Iwe-irohin rẹ ti Gẹsi *Lagos Weekly Record* ti ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu *September* tokọja, o kọ ọrọ kan eyiti a sọ pe o fi digbolu dida ṣeria ni kotu Ọba King; nipa ohun ti o ṣẹlẹ yi ki enikẹni maṣe ro pe Ijọba nfẹ pa gbogbo awọn Oniwe-irohin ilẹyi lẹnu mọ pe ti nwọn ba ri ohun kan ti o dabi o ku diẹ ki o to ki nwọn maṣe sọ, bẹkọ rara; nigbati awa papa ka Iwe-irohin ti a wi yi, ẹru ba wa gidigidi pe o le bi Ige o si le bi Adubi; ofin Ijọba *Nigeria* ko ṣai fun Oniwe-irohin kọniwe-irohin laye lati mã ṣiṣẹ rẹ bo ti tọ ati bo ti yẹ; igbagbọ wa si ni pe ninu gbogbo Ijọba Oyinbo to mbẹ lode aiye nisisiyi, iba ṣe Ijọba Franse ni, tabi Ijọba Jamani tabi ti awọn Pàyãn, kosi eyiti o lãnu, tabi ti o ni inurere bi Ijọba Gẹsi eyiti a ni ori rere lati wa labẹ rẹ. K'Ọba King k'o pẹ!

Eṣu ṣe Oniwe-irohin kan k'o jẹ k'oyo tan ni ilu ti Jamani nṣe oluwa wọn gẹgẹ bi *Cameroon* tabi *Duala* ṣiwaju ogun-Ajakaiye, ki irufẹ Oniwe-irohin bẹ sọ pe on kọwe ẹlẹsinrin kan lati ma fi aṣiṣe Ijọba Jamani han wọn, bi lọgan kọ ni nwọn yio fimu finlẹ wà irufẹ ẹni bẹ kan ti yio si ti gãsi rẹ b'awọ: tani nj'enia? Loju bilala mẹrinlelogun pẹlu ọkan fun *Kaiser* Ọba wọn! Ọgbẹni kan ti o ma nsaba kọwe ohun ti oju rẹ rito sinu Iwe-irohin kan ti a npe ni *Gold Coast Leader* eyiti a ntẹ ni *Cape Coast*, nipa ohun ti o ṣẹlẹ ni ilu kekere kan ti a npe ni *Togoland*, lè gbagbe iwa ti awọn Jamani hu si ẹnikan tí nwọn fura rẹ ni ilu na pe on lo ntu aṣiri wọn han fun gbogbo enia ka, bi awọn Jamani ti rẹlu il[e] Ọgbẹni ti nwọn fura rẹ yi pe boya ọw[o] wọn le tẹ awọn iwe ti o nkọ na; ṣugbọn a dupẹ pé ti Ijọba Gẹsi ko ri bẹ; Ijọba Gẹsi fun Oniwe-irohin laye lati ma sọ ti ẹnu r[ẹ] fun rere ilu ati fun riran Ijọba lọwọ; ṣugbọn bi irufẹ Oniwe-irohin bẹ ba nk[ọ] ni ikọ-amọrewọ alugbẹdu ti ko ṣọ ede ti [o] fi nkọ Iwe-irohin na lo, ti o si dabi ẹnipe [o] nkọ ni ikọ Afojukamọ tabi ni ikọ Tani-t[o] mumi, eyiti o mu Afojudi dani fun Ijọba nigbana ni ijẹgbọn de si irufẹ Oniwe-irohin bẹ.

Ẹ tun kiyesi o, Ijọba Gẹsi ko da ẹni[kẹ]kẹni lẹkun lati sọ ti ẹnu rẹ ninu Iwe-irohin ṣugbọn etutu ti o wa nibẹ ni pe ki oniyẹn m[a] ṣe mẹlọmẹlọ ki ọrọ ma ba gbe sọ nipa l[i] ede alufaṣa tabi ede ti awa papa ko jẹ g[b]funẹnikeji wa ambọsibọsi ẹniti o wa lab[ẹ] wa, bi a ba ṣẹgi nigbo o yẹ ka fi ọran [si] ara ẹni wo; b'ode ba d'ode ẹni ko yẹ k[a] fi daran, àrán ni ki a fi da.

A tanma pe gbogbo awọn ti nwọn n[i] ara wọn ṣẹsin nipa fifi kalamu kọ ik[o]kukọ bi ọrọ ẽbu lorişirişi ti nwọn si ro p[e] nwọn nṣe nkan gunmọ loju ara wọn, nip[e] pe ki enia mã ro pe awọn na nkọwe s[i] Iwe-irohin diẹ, yio fiyesara ohun ti o ṣẹlẹ lo[ṣẹ] tokọja yi; gbogbo ẹniti nkọwe sinu Iw[e]-irohin kọ ni ọmọwekọ, eyini bẹ; bi atẹgu[n] ba ndamu ologi, ko ha yẹ ki oniyẹfun n[ṣ]ọra bi? Bi ajayika-iji ba ndu aṣọ n[i] ọga lara, ko ha yẹ ki awọn abẹyọ rẹ n[i] tun aṣọ lilọmorun wọn so bi?

A kẹdun ohun ti o ṣẹlẹ yi gidigidi, ohun kan ba si wa ti a le kọ bi ẹkọ ninu ohun na nipe Iwọntunwọnsi ko'go ja ni ohun gbogbo.

Lati oni lọ ẹ jẹ ka ma ṣafarawe Ala[p]ndẹdẹ ti o ni on njaiye lọbẹ́-lọbẹ́.

---

## LO FEREFE, LO FEREFE, ỌKỌ-ONIDAN, LO FEREFE!

Girigiri-ẹsẹ ni a sọ pe dide awọn ọkọ-ofur[ufu] mẹta si Kano lati ilẹ Egypt ninu ọsẹ yi, ṣe a[wọn] ara-ilu Kano yi. Ọkẹ-aimoye-enia ti nwọn s[i] rọwo ọkọ wọnyi pọ to bẹ ti a fi sọ pe rakun[mi] tabi ẹṣin tẹ ẹnikan rẹ, ti awọn si gbe l'ọgaf[un] sile alarun. A sọ pe bòya awọn ọkọ abami wọ[nyi] le wa fi onjẹ oju foju l'Eko nibi.

## NIGBAWO!

[*Lati ọwọ* KEKERE ILU.]

Si Oniwe-Irohin *Eko Akete.*

Iba o!

Gẹgẹbi dide Gomina titun, Ọlọla Graeme Thomson, si arin wa ti sunmọ etile a ni tanmọ pe gbogbo ẹn ti ifẹ rẹ ba wa fun ire Ilu ni yio wa-wọ ọtẹ ati rikiṣi rilẹ ki Ilu le roju ni akoko ti a ma bọ si yi. Ṣugbọn o ṣe wa l'oju su pe awọn ti nwọn iba jẹ atọni-sọna ko yi ti bọ ẹwu ija wọn silẹ.

Awon kan ṣi nwi awi-dabọ ọrọ to ti ku. nwọn nwa yara titun ka awọn Oloye Eleko, nwọn si ntari Eleko titun si iwa ti ko tọna. Gẹgẹbi ẹnikẹni ti le mọ, Ilu wa yi kere fun Ẹgbẹ Ilu janrẹrẹ ti nwọn ma ma gbun ara wọn, it nwọn si ma nra ṣe kokowa pọ. Bakanna si ni o jẹ mimọ fun onilakaye pe a ko le fi agbara so Ilu pọ, bẹni ofin ko si si fun Ijọba papa ki a ma ṣẹṣẹ wipe Eleko titun ti a sọ fun l'oju t'aye pe ko ni agbara ati aṣẹ lori ẹnikẹni ni Ilu, lati pa Ẹgbẹ ba kan rẹ tabi lati tilẹkun mọ Ẹgbẹ kan. Ẹgbẹ to fẹ ru Ilu tabi to fẹ da ija silẹ awọn Ọpa Ọba papa lo ma fi Ẹgbẹ bẹ sun ki Ijọba to da sẹ le e. Bawo lo wa ti le ri ki Ọba Eleko titun ti aniyan rẹ nisisiyi ni lati wa lori ajo ati da gbogbo Ilu pọ sori alafia, ki o wa sọ pe on ko fẹ awọn kan ni Ilu, Ilu ibo o? Idi ti a fi bere pe "Nigbawo?" ni eyi. Nitori o tọ ki a bere igbawo lo da ti a o wa iṣẹ rere ṣe? Igbawo ni a o bẹrẹ si wa alafia Ilu? Ire ni a nwa nigbati a ngbe awọn Oloye Ilu gbun igba, gbun awo? Ko si ire ninu iyẹn. Ti pe ki awọn Oloye ma si ninu Ẹgbẹ Ilu kankan, awọn ẹlẹgbẹ wa miran ti da ni amọran ri, lọna to ye ni. Ṣugbọn ohun ti a ni lati ranti ni ipo ti awọn Oloye ati awọn ara Ilu wa. A kan nsọ ni, diẹ ninu awọn to mọwe papa lo nronu jinlẹ, diẹ lo si ni ero tirẹ ati aye lati sọ t'enu rẹ ati lati duro lori eyi ti ọkan rẹ ba sọ. Pupọ wa ni ki yẹ ọrọ wo to ki a to gbe ogun ija kari. Eyi to si buruju ni pe awọn ti nwọn nfẹ ki enia gba ọrọ awọn ko ye ninu isọkusọ ati iwakiwa. A ko le fi ẹtanu sọrọ ọta ẹni ki aiye gba ọrọ na si ọrọ ọdodo; bẹ l'a o si le fi ohun akọ fi ọrọ ye enia. Ẹwẹ, ẹniti ko ye wa "jọmi-jọmi" hu ko le tete ri ẹni tẹle e. Iyẹn bẹ.

Ti awọn to nfẹ tubọ ko ba awọn Oloye wa ko joko si bi kan O ku ti awọn Oloye na ntẹle, a fẹ ki Ilu ma ka ọrọ wa wewọ nitori ọrọ ijọmiran.

Eyi to ti kọja ti kọja. Eyi to mbọ lẹhin li a ko yi mọ. Nitori eyi to mbọ lẹhin—eyi to ku lẹhin ọfa ṣa ju oje lọ—ni a ṣe nsọ yi. A mbẹ awọn atọkun Ẹgbẹ Tunluṣe ki wọn jọwọ fi ọwọ giri-giri di Ẹgbẹ mu. Fifọ Ẹgbẹ itiju gbogbo wa ni nitori awọn Oyinbo yio ri'un wipe a ko le dá so. Ẹgbẹ Tunluṣe fẹ ifẹṣẹ rinlẹ. Eyi ni pe ki Ẹgbẹ mọ ipo Ijọba fun Ijọba, ki o si ṣe ẹtọ pẹlu ọran Ilu. Olotọ ti ẹru enia ko ba ba yio gba wipe ni Eko yi, awọn Oṣelu to pin rawọn si meji ti olukuluku si nfi ogun gbari pe rere l'awọn nwa rere l'awọn si nṣe ni ko gba ọna ẹtọ. Awọn apakan ngun Ijọba ni kẹṣẹ lati maṣe wo awọn apakeji l'oju're arara. Awọn keji, ẹwẹ, to si ni awọn wa fun Ilu, nwọn ko fi ọna ẹtọ gbeja Ilu lọdọ Ijọba. Nisisiyi wayi ti gbogbo rẹ wa bu mọ'wa lọwọ ti a si wa ri pe asẹhinwa-asẹhinbọ, ti Ijọba laṣẹ, ko yẹ ki a kan dẹkun ija nikan. O yẹ ki a tun ipalẹ Ẹgbẹ papa ṣe ki iduro rẹ le ṣe giri. Otitọ lo si yẹ ki a fi ṣe atunda ina Ẹgbẹ na. Ipade Satide tọhun ko ri bi ti eṣin. Meji tọtọ ninu awọn Alagba alakoso Ẹgbẹ l'a si fẹ ku l'oke. Ti ẹnikan ṣoṣo ni nwọn sọ. Iyẹn ni ti Ṣingulu. Ohun ti awọn si sọ nipa Ṣingulu ko murọ. A fi Ṣingulu jẹ oye miran ki nṣe sababi aiwa sẹgbẹ. Nkan wa nidi rẹ. Eyi yi fẹ ayẹwo ati atunṣe. Ko to ki Ẹgbẹ sọ awọn mejeji ti a yan si Igbimọ Ilu nu aiba won ṣepọ mọ yio ni Ẹgbẹ l'ara ni, awọn Alagba Janma ti Iwe kan si sọ pe nwọn ko yẹ alukawani wọn nfẹ kikesi lati mọ ẹdun wọn ki atunṣe tun wa nibẹ pẹlu. Ohunkohun t'o ba ba fifasẹhin wọn wa ni lati jẹ mimu kuro a mọ pe Ọlọrun Ọba nikan ni nkankan ko le ṣe laisi Rẹ. Ṣugbọn sibẹ na a ni lati jina si iwa a nko iyan ara ẹni kere. Ẹnikẹni to wun to nhuwa ibajẹ ti nkan na fi di sege-sege a ni lati fi gun oluwarẹ lojo, ki a si fun u ni Ofin, nitori ẹni nle enia junu ko tun Ẹgbẹ ṣe Ọranyan ni ki a pẹtu si ọrọ gbogbo ki a fi ewe agbejẹ le ẹnikẹni to ba nṣe aṣeju lọwọ. Awọn ọta nyọ ni nigbati ọran Ẹgbẹ Tunluṣe ba ndi ogun "Hawu, ṣe ikọkan ni ẹwọ nyọ!"

A ke si awọn atọkun Ẹgbẹ Tunluṣe ki nwọn fi ọran Ẹgbẹ ṣe ọrandun nitori bo ba bajẹ, awọn ni o! K'Ọlọrun ba ni tun gbogbo rẹ ṣe o.

Gomina titun mbọ o, bi a ba ti ṣe si bẹ na ni on papa ma fi ṣe si wa o, Bi a ba duro bi "I" iyi na yio pọ pupọ. Ṣugbọn bi a fi ẹtẹ silẹ k'a npa lapalapa—K'Ọlọrun ṣọ wa ninu rẹ.

Ngbawo l'a o ye iwa jagbajagba hu? Isẹnyi na lo yẹ. Igbayi gan l'a ni lati tọju ka mu ọna iṣẹ rere, iṣẹ atata pọn, ko le yẹ Ilu wa ki o ba le yẹ wa. Iba o!

### AKIYESI.

Irohin idajọ Ogbẹn ati aṣiwaju wa Thomas Jackson, ti Megida sọ ṣọ'ki l'ọsẹ to kọja, ṣe *Kekere Ilu* l'anu pupọ nitori ipo ti Oniwe-irohin na wa larin wa. Lotọ, nko ri si ọna to mu lati ẹnu igba ọrọ Ilu ti daru. Eyi yi ni gan lo jẹ ki agbako to ba a lọsan gangan yi dun mi kan egun. B'enia ba ma jiya, o tọ ki ọkan on papa da a lare; o si tọ ki o jẹ iya lori ododo. Jackson ti ṣe kasikan iṣẹ fun Ilu wa. Baba rẹ si ni ọkan ninu awọn Akọni nla ti a ti ni ri. Iṣẹ ti Baba rẹ ṣe ku l'otẹle. Ṣugbọn o

yẹbá lọna tara to ti mí a bọ l'atẹhinwa. Abọ rẹ si ni iya ajẹdanu to njẹ nisisiyi. A ṣọrẹ lọwọ Moore, Taylor ati awọn Loya yoku fun aniyan ati ajo wọn. K'Olọrun mu ẹni wa na bọ l'alafia, ki ile awọn ọrẹ rẹ ati ọna wọn muṣẹ l ajẹ. K'Olọrun bukun wọn. A tun sọ pe anu nla ni ijiya rẹ ṣe wa.

Ẹwẹ, a gbọ pe awọn Oloye lọ sọdọ Balẹ tuntun a ko yi gbọ abọ dada. Iba bi a ti gbọ si ni pe Balẹ gba ẹbẹ ti abuku ti Ijọba ni nwọn ta fun wọn nigbati Cliffcrd nlọ, ṣugbọn oṣu meje ti kọja ki nwa. Abere ẹhin. Nwọn dahun pe awọn kọ mọ ri ni, ko ye awọn. Ṣugbọn nigbati Jonsi bere ni Igbimọ, idahun to gba wa mu u ye awọn. Balẹ ni nwọn ko ti fi ye wọn ri lọ jẹ yẹn. Ilu yio ranti pe a ti so nibiyi ri pe ki awọn alabaro awọn Oloye jẹ ki awọn Alagba tobi Aṣẹju wa wadi ọrọ. Ẹnu asọṣẹko ki nṣa to ilẹ. Nisisiyi, ki awọn Oloye wa le jẹ Oloye Ilu, nkan gbogbo ni lati tù, kò tà. Iyipada to wa ni lati ba wọn lara mu. Nwọn ni a ki bọ s'ómi tan k'a tun ke otutu. Abọ ọrọ ni o, o dọwọ awọn Oloye papa. Nigbati ọran ẹbẹ tun nisisiyi awọn tikalawọn lo da lọ. Bi iyẹn ko ba to fun wọn lati di ẹrù won mu funra wọn, o dọwọ wọn o. Eletu, Oluwa, Olumẹgbọn, Ọlọtọ, Oṣodi, ti Iya nyin d'ọwọ nyin nisisiyi o. Bi ẹ ba pari rẹ li eyiti ẹ ti dawọle yi yio san pupọ, yio si rọ nyin Forum. Ki Oluwa ma fi iya ọna mẹfa jẹ nyin o, ki Oluwa le tu Ilu ninu! Ẹ gbe e ja o!

KEKERE ILU.

---

***THE EDITOR'S OBSERVATORY.***

---

**Legal year at Christ Church Pro-Cathedral.**

Both the Bench and the Bar were present at the Service which was held at Christ Church Pro Cathedral in the morning of Monday last, when Rev. M. S. Cole M.A., Vicar of Christ Church, preached an eloquent sermon from II Chronicle chap: verses 6 & 7.

Of the Bench we noticed His Honour Sir Ralph Combe Chief Justice, His Honour M. L. Tew, Judge, Messrs. A. D. A. Macgregor, Acting Attorney-General, Blackall, Solicitor General, His Worship M. C. Greene, Police Magistrate Lagos. His Worship H C. Young, Police Magistrate Ebute Meta, Major Walker, Acting Inspector-General of Police, F. W. Garvey Esq., Director of Prisons.

Of the practising Bar, the Hons. Eric O. Moore, Kitoyi Ajasa, Messrs. J. T. Nelson Cole, N. W. Holm, E. M. E. Agbebi, Adedapo Kayode, A. Latunde Johnson, Sigismund Macaulay, Ayodele Williams, A. Abayomi, A. Desalu, S. H. Baptist Caxton Martins, A. O. Thomas, Messrs. J. H. Stanley Robbin, Chief Registrar, T. B. Buko, Assistant Chief Registrar.

Mr. Chancellor Carr read the lesson Rt. Rev. Bishop Oluwole and one European clergyman appointed for the day, read the prayers; whilst the Bishop of the Diocese pronounce the benediction.

IROHIN KO TO AFOJUBA.

---

